# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 563 TUESDAY, MARCH 24, 1964 (2D)


## Waya Ina Ẹlẹntiriki Pa Obinrin Kan

SHOMOLU:— Ariwo nla ta, jinnijlnni si dabo gbogbo enia nigbati Iyawo-ile kan, Iyaafin Christain Balogun, ti o ngbe nọmba 32, Ọlabiran Street, subululẹ ni ojiji nigbati o de lati baluwẹ ti o si ku bamubamu ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi.

Irohin awọn Ọlọpa Shomolu ti ye wa wipe ọmọ ilu Ibinni ni obinrin na, o si nṣiṣẹ akọwe ninu Ile-iṣẹ awọn Oyinbo onisowo kan l'Eko.

Nigbati obinrin na ṣiwọ de lati ile iṣẹ rẹ, ti o si bọ ara silẹ tan ni o ba lọ si baluwẹ ti o si lọ we nitori ooru ti o mu u.

Ṣugbọn nigbati obinrin na wẹ tan, ti o si nbọ lati baluwẹ, ni o ba tẹ okun ina ẹrọ-asọrọmagbesi kan mọlẹ laimọ, lojiji ni obinrin na ba ṣubululẹ, ti ariwo awọn ara ile ta ti okiki si kan ba awọn Ọlọpa ni Tesan.

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ara ile na ba nṣe najo obinrin na ni orisirisi ọna, ṣugbọn bi awọn enia na ti ṣe wahala to ofo ni gbogbo wahala na jasi. Obinrin na ko le ta wuyẹ nilẹ mọ o si ti ku bamubamu.

Awọn Ọlọpa ti gbe oku obinrin na lọ si Ile-iwosan lakulaku Ikẹja fun ayẹwo awọn Dọkita, nwọn si nṣe iwadi ọran na lọ lọwọ, bi nwọn ba ti ri idi ọrọ na si ẹo ma a gbọ o.

# APAPỌ IJỌBA NAIJIRIA FẸ FI OWO KUN OWO ỌJA

EKO:— Nikutukutu owurọ ana ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni Apapọ Ijọba Naijiria ti nwọn wa ninu ipade nisisiyi fọwọ ṣi iwe ofin kan ti Oloye Festus Okotiẹ-Eboh, Minista Alamojuto Eto isẹ inawo fun apapọ Ijọpa mu wa ṣi ile Igbimọ pe ki Ijọba fi owo kun owo awọn ọja.

Oloye Festus Okotiẹ Ẹboh, "Omimiejo" lo mu aba na wa si Ile-Igbimọ wipe ki Apapọ Ijọba Naijiria o fi ọwọ si iwe aṣẹ na ki nwọn si sọ di ofin.



Oloye Festus Okotiẹ-Ẹboh
Minista Alamojuto Eto Inawo
Apapọ Ijọba Naijiria

Ṣugbọn gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na ti o wa lori aga Ijọba ati awọn Alatako ni nwọn lodi si ofin na.

Ninu ọro wọn, awọn ọmọ Ile Igbimọ na ṣe alaye wipe, ko yẹ ki Ijọba tun fi owo kun owo awọn ọja ni asiko yi, paapajulọ awọn ẹsẹ mọtọ (taya.)

Awọn ọmọ Ile Igbimọ na ni ọna ti Minista na gba lati gbe ofin ifowo—kun owo ọja yi kọ ba ofin mu ko si yẹ ki iru rẹ o waiye ni iru asiko yi rara.

Nwọn tun ṣe alaye siwaju wipe gbogbo awọn ẹsẹ mọto-taya ti nwọn nṣe ni Naijiria nisisiyi ko dara to awọn eyi ti nwọn nṣe wa lati ilu Oyinbo.

Awọn ọmọ Ile Igbimọ na fi ye gbogbo Ile wipe. ti awọn ba ra taya ti nwọn nṣe ni Naijiria ti awọn ba lo o fun oṣu mẹta taya na yio bajẹ.

Bẹ si ni ẹwẹ, ti awọn ba ra awọn taya ti awọn Oyinbo nṣe ti o nwa lati ilu Oyinbo, awọn nlo iru awọn taya bẹ fun ọdun mẹta tabi mẹrin nigbamiran. Nwọn tun ṣe alaye wipe, iye owo kanna ni awọn onisowo ti o nta awọn ọja na nta wọn ko si iyatọ lori iyo owo awọn mejeji.

Awọn ọmọ Ile Igbimọ na ni o yẹ ki iyatọ wa larin iye owo ti awọn ara ilu yio ma a ra awọn ọja ti nwọn nṣe ni Naijiria ati awọn ọja ti o nwa lati ilu Oyinbo.

Oloye Akin - Olugbade ti iṣe ọkan ninu aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu Ile Igbimọ Asofin na ṣe alaye wipe ọpọlọpọ ni awọn onisowo ọmọ Naijiria ti nwọn ti ranṣẹ ọja lati ilu Oyinbo, ṣugbọn lati igbati awọn ọja na ti de si Ebute okọ Oloye Akin-Olugbade sọ wipe, awọn onisowo na ko ti ri owo fi gba awọn ẹru na titi di bi on ti nsọ yi.

Oloye Akin-Olugbade tun ṣe alaye wipe, ọpọlọpọ ninu awọn ẹru ti o wa ni Bode na ni i awọn aloku taya ẹsẹ mọto ti awọn onisowo ti nwọn ko ni owo lọwọ lati fi ra taya mọto titun.

Eyi lọ mu awọn enia na ranṣẹ si ilu Oyinbo, sugbọn nigbati awọn ẹru na de ti Ijọba ti fi owo kun owo ẹru, awọn onisọwo na ko le lọ gba awọn ẹru na ni Ebute ma.

OKETE ẸRU

Oloye Akin—Olugbade tun ṣẹ alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe ti ọrọ yi ba ru ẹnikẹni loju, ti oluwarẹ si fẹ mọ idi okodoro ọrọ na o ni ki oluwarẹ lọ si Ebute ọkọ ki o lọ wo awọn okete eru ti o wa nilẹ

Lẹsẹkẹsẹ ni Oloye Festus Okotiẹ-Ẹboh dide ti o si sọ fun gbogbo Ile Igbimọ na

Wo Oju Ewe kefa.

## Dokita Majẹkodunmi Di Oloye

ONDO:- Irohin ko to afojuba ni ti inawo Oye ti Olola Dokita Majẹkodunmi, Minista Alakoso Eto iṣe Ilera fun Apapọ Ijọba Naijiria ṣe lẹnu lọloyi ni Ondo.



Gbogbo awọn enia jankanjankan ni nwọn wa sibi inawo ọjọ na pẹlu awọn ọba, Ijoye Adajọ ati awọn enia sarakisaraki

Oniwe irohin wa Ejo'ngboro ti o lọ sibi inawo ifije oye na fi ye wa wipe awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na l: ni ẹgbaa mẹrinla enia (26,000)

Bi awọn enia na ti pọto ajẹti ati amuti ni nwọn fi onje ati ọti mimu ṣe. Oloye Majẹkodunmi ati Oṣemawe Ọba Ondo ni ẹ nwo ninu aworan yi.

Awa Oniye irohin Imọle ki Oloye Majẹkodunmi ki orire, oye a mọ ori o.

# IWE SI OLOTU

## Nibo Ni Ẹrukobodo Wa?

u Ọjọ mẹta kan ẹsi ku igbadun Olotu, Ọlọrun ko ni gba on nyin fun ẹlomiran o asẹ. Nba dupẹ ti ẹ ba jẹ gba mi ni raupẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ lati bere Ọgbẹni wa Erukobodo awọn ti o ba mọ ibiti o wa.

a ba nri enia ti a ko ba n ri Oluwarẹ mọ, ẹtọ ni ki ẹ ibiti oba lọ Bakanna ni ti nka ọrọ enia ninu iwe Iro-kan lasikolasiko ti a o ba si ri ọrọ rẹ ka mọ ẹtọ tun i abere Oluwarẹ.

rọ ati itan Ọgbẹni Ẹruko-o mu atata Ọgbọn lọwọ, bere rẹ, Ọgbẹni na nsọ ata-rọ sinu iwe Irohin Imọlẹ. bi o ba lọ si irinajo o tọ, yẹ kia ri ka ninu iwe Iro-Imọlẹ tabi ti oba si ti di



ẸRUKOB'ODO

ba ninu iwe kikọ pe, bọya sin mi ninu iwe kikọ sinu iwe ohin ni o yẹ ki gbogbo awa ti nka Irohin Imolẹ mọ.

Nitoripe, o titọ Ọpọlọpọ Ọdun Ọgbẹni Ẹrukobodo ti nsọrọ nu iwe Irohin Yoruba, gbogbo a ni a si ngba awọn ọrọ rẹ na jọwọ Olotu ni ibo ni Ọgbẹni rukobodo lọ o.

Emi ni
TIJANI

badan.

asiwaju ilu yi saba ma nhu larin ilu.

Iwa tani yio mu wa eyiti nwọn ki hu larin ilu miran rara.

Ọpọlọpọ awọn kansilọ ilu lọ saba wa kakiri ti nwọn si ma wọle lati mu Ọti larin ilu, ti nwọn si ma tilẹ rin irin alai loju ti.

Iru iwa yi ko yẹ enyin oṣelu rara.

Inu mi yio dun ti ẹba le so idi ti ẹ fi nṣe bẹ? Tabi ẹ tun fi ọti mimu ṣe Oṣelu ni? Kaka ki ọsan lara Iya ajẹ o fi gbogbo ọmọ rẹ bi Obinrin, ẹiyẹ nyi lu ẹiyẹ.

Notiri idi eyi mo kesi awọn onisẹ Ibajẹ wipe ki nwọn da Iru Iwa bayi duro

Emi ni,
ALFRED OLAREWAJU
Ogbomọsho.

## Mo Fẹ Lati Ra Iwe Ijala

Olotu, yio dun mọ mi lọpọlọ-pọ ti ẹ ba le gbami laye lati tẹ iwe mi yi jade fun gbogbo awọn Onkawe Irohin Imọlẹ yi ka.

Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun pe ati ri awọn akikanju enia bi Ọgbẹni Oladipọ Yemitan ti nwọn ṣa awọn aṣa ilẹ wa jọ fun kika awọn ọmọ wa.

Iṣẹ nla ni Ọgbeni Yemitan ṣe, nitoripe awa na mọ gbogbo wahala ti o wa ninu ati le kọ lẹta atun nbọrọ ati le kọ odidi iwe jọ lori Ijala.

Mo dupẹ pupọ lọwọ nyin o, Olotu,

Emi ni,
KARIMU OYEDEJI.

Ilaro.

## Ẹ Kilọ Fun awọn Ọmọ nyin

Ẹ jọwọ, ẹ gba mi ni aye lati ba awọn obi sọrọ atata paapa awọn obi ti awọn ọmọ wọn nwọ ọkọ akero to njẹ bọọsi pe ki nwọn kilọ fun awọn ọmọ wọn na daada. Nitoripe Iwa ti wọn nhu ko dara to rara.

Ti awọn ti ngbowo ninu Bọọsi na ba ni ki Inwọn wọle, nwọn a taku lati wọle, nwọn ko si ni gbọran si wọn lẹnu rara. Nwọn fẹ-ran lati ma sare mu bọọsi lori ere, ki nwọn ma rọ bi adan.

Mo bẹ ẹnyin obi pe, ki ẹ fa awọn ọmọ nyin leti, ki ẹ kọ ọmọ ni ẹkọ ile, ki ẹ,la ye wọn pe, emi ko pe meji. Asiko to lati ma ku awọn ọmọ wa ni bi a ti ṣe nhu iwa ni arin ẹgbẹ ati ọgba pẹlu.

Ọpọlọpọ awọn obi ni ko kọ ọmọ rẹ rara nwọn o de ọdọ oluk-ọ wọn, nigbati obi ko kọ ọmọ rẹ, bawo ni olukọ ti ṣe le kọ? Obi ni o nfun ni onjẹ, o nra aṣọ fun o tun ngbọ bukata. Ẹ ma sọ ẹru ti oyin di ti olukọ mọ.

Emi ni,
ABIỌDUN,

Eko

## Iwa Ibajẹ Pọ Ni Ilu Ogbomọsho

Olotu, Jọwọ gba mi laye lati sọ dun okan mi ninu iwe Irohin nyin Oloyin mọ ọ fun awọn ibanijẹ ilu Ogbomọsho ti nwọn nfi iwa ibajẹ se iwa hu ti nwọn ko si ri enI sọ fun awọn.

O jẹ ohun Iya lenu fun mi ati fun gbogbo awọn enia lati ma ... iwa buburu ti awọn ti Oje


BERE OJULOWO EGBOGI:—

**Congreve's Female Remedy**

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirnu nigbakugba tabi ni ẹkọnkọn ẹhiu-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu lara tabi aikofọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba-aiya riru ọmu riro wiwo, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi-oju Ilaogun ara jẹ ẹsẹ ara sisọn gbori abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun tọju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera idi iọ ati orisirisi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

**mmoniated Quinine Tincture**

Nigba lailai ki awọn Orisirisi sọbirọki egbogi ti wọn uko wa nisinsinyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi iwe egbogi yi bi otutu kọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji aibui ba nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danju ni bi oba ti ta de sini omi ti o bọwosọ ki o si gbe u sare egbogi otutu ti o daju fun itọju eti rirọ tabi didun, to Akokoro. egbogi ti o ma njọ apo-ie-itọ tabi se iwosan iyọuu ayọ-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọwa-ọfun didun ati orisirisi omiran pẹlu bere ni ṣọbu awọn:—

Waterloon Mdicine Stores
8 Palm Chuch Street, Lagos.
Phone: Nigeria, (Oja Ita Faji)

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHALET**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO

Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọn-mọnọ




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faraose ati i awọn Tatambulu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu

Bere egbogi ajẹbina Payal yi ni ṣọbu wọnyi:—
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)
(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street Yaba

# AṢẸWO KIṢE IṢẸ RERE

Lati Ọwọ:- JOSSY BABA, IGBOMINA

Ki nto bẹrẹ ọrọ mi, mo fẹ juba awọn enia nla ati awọn alaiye, ki njuba Ọlọrun Olodumare. Mo juba, nigbati ẹla-ilẹkẹ kojuba ni ọmọ araiye fi nsọ pe, ẹla ilẹkẹ kolo-ju afokunbọ, nigbati agogo kojuba lọjọ kini ni ọmọ araiye fi nsọ pe. agogo kiroju pewe, mojuba fun ẹnyin ẹda Ọlọrun ati ọmọ enia.

Ile aiye ti baje, iwa eri pọ ninu rẹ, ọmọ ọdun mẹwa ti nloyun, asẹwo ti gbagbe pe igba ko tọlọ bi orere aiye ki tọlọ bi ọpa ibọn, tolo ose bi owe

Asẹwo ti gbagbe alẹ nwọn sọ idi di sọbu, nwon ko fẹ iṣe se mọ, ẹti fi gbogbo akoko sowo asiko ti ẹba ronu ẹko ronu rara, bẹni ẹniti ko ba jiya ko le jọrọ laiye.

Mo fi Ọlọrun bẹ nyin, ẹ ronu nyin wo daada ẹo le fi ọgbọn ọdun sẹwo ti ẹo fi di ẹgẹrẹmiti irun yio tan lori, oju ko ni dan mọ ara yio hun jọ abẹ yio domi ati bẹẹbẹ lọ. gbogbo awọn okunrin ti ẹnwu ẹo ni wu wọn mọ.

Bi ọlọmọ ba nkọmọ asewo yio lọ wọ "bonfo" ko ni ronu pe, on na nfẹ ki nwọn ki owa ko ọmọ ti on na rara Oyẹ ki ọmọ fi ti awọn obinrin ẹlẹgbẹ rẹ ṣe ẹkọ kọ, ko ni se yẹn rara, afi ki ọmọ se ise-kuṣe nigbo gbo igba.

Nwọn ko bẹ Oluwa pe, ki ọmọmu ọyan laiya awọn afi ki ọmọ ka (akisa) kọseti jọ bi nkan gidi Bi ẹwu ba yọ nisalẹ ori. ọjọ ẹlẹya de

Lẹhin ọla asẹwo yio wa mọ wa ọmọ nwọn ati gbagbe pe oti bọsori ko si okunrin ti yio sunmọ arugbo asẹwo.

Bi nwọn ba tati nwọn amọ hu ọkunrin pe. ko ni asọ lọrun awọn ni o mọ oni mọto, onikẹkẹ ati ẹniti nrinlẹ.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 21 - Feb 19) Fi oju si awọn eto iṣẹ ti owulo fun ọ lati ṣe fa sẹhin fun awọn iṣẹ ti ao pe ọ si lai pe ojo

PISCES (Feb 20 – March 20) Mura lati wadi ọtitọ nipa ọrọ ti yio ṣẹlẹ si ọ, ṣe otitọ nipa awọn ohun ti yio tẹ ọ lọwọ.

ARIES (March 21 – April 20) Iranlọwọ kan yio de bao lati ọdọ ẹnikan ti o ko lero. ṣugbọn bi o ba fi ọkan re bale alaja yio de ba ọ.

TAURUS (April 21 -May 21) Maṣe gboju le awọn ọrọ ẹhin ti nwọn yio ma ba ọ sọ. Nitori pe gbogbo ohun ti o ba nro ni ọkan rẹ rere ni yio ma nyọri si. maṣe ro ero kero lọkan ki ohun b buru naa ba ṣe de ba ọ loni.

GEMINI (May 22 - June 21) Ọpọlọpọ ero kan yio de ba ọ nipa ọna iṣẹ rẹ. Mura lati doju kọ ohun ti yio ṣe ọ ni anfani.

CA CER (June 22 - July 23) Fi ọjọ oni simi, yio si rọ ọ lọrun. Ma ṣe jẹ ki ariwo awọn aladugbo di ọ lọwọ rara.

LEO (July 24 Aug 23) Irohin rere kan yio kan ọ lọwọ nipa ọna owo rẹ, mura lati doju kọ iṣẹ rẹ loni.

VIRGO (Aug 24 - Sept 23) Ọjọ oni yio dara fun ọ ṣeto lati le fi ọkan rẹ ṣe otitọ larin awọn aladugbo rẹ gbogbo,

LIBRA (Sept 24 - Oct 23 Gbogbo awọn iṣẹ rẹ ti o fẹ lati da wọ le yio yọri si rere. Mura lati ṣe gbogbo awọn aṣeti iṣẹ rẹ gbogbo.

SCOPI (Oct 24 - Nov 22) Ọjọ oni yi jẹ ọjọ ti yio rọ ọ lọrun lati le ba ayanfẹ rẹ sọrọ ti o fẹ, ọrọ nyin yio si wọ ara wọn.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 22) Ọrọ ti oba olufẹ rẹ sọ yio bọ si, eyiyi yio si fun ọ ni itẹsiwaju nipa adehun nyin.

CAPRICORN (Dec 23 - Jan 20) Iwọ yio ri idi-wọ ni ẹnu iṣẹ rẹ lati arọ titi di ọsan gangan; ṣugbọn lojọ ali gbogbo rẹ o rọrun fun ọ.

# AKARA TU S'EPO !

## Iwe Itumọ Ala na ti de !!



Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pẹlu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

J. O. SHOYINKA
N2/99 Shittu Street
Ibadan

# EGBOGI JẸDIJẸDI

ERE FUN EGBOGI



## "CYCLEVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ o si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru 'ni pataki fun Ọkuarin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jedijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ. ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna ṣẹlu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa. ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnse, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "GYCLOVFN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣẹ wa idi rẹ ra ki o si danwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi to wa ni igboro ilu Naijirisjakejado. Bere rẹ ni:-

Waterloo Med cine Store
8. Palm Church Street Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# Ẹgbẹ Afẹnifẹre fẹ ki Oloye Akintọla pe ipade ile Aṣofin Iwọ Orun

IBADAN:— Ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G.) ti kọ iwe kan si oloye Akintọla ti iṣe olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pe ki o tete pe ipade kini ti ọdun ti igbimọ aṣofin Ipinlẹ Iwọ Orun lati le ṣe iṣiro owo nina ti ọdun yi.



amugbalẹgbẹ re tete pe ipade Igbimọ aṣofin Ipinlẹ na O tun fihan wipe kosi ẹniti wah-la awọn ẹgbẹ Dẹmọ yi yọ lenu nitoripe nwọn sọ pe awọn ẹgbẹ Dẹmọ yio ni ijọba ati pe awọn lo pọ ju ninu ile Igbimọ aṣofin ipinle na, Alhaji Adegbenro tun sọ pe, ogunlọgọ awọn oṣiṣẹ Ijọba Ipinlẹ na ni wọn njiya nitoripe ko si i g b e g a fun wọn lenu iṣẹ wọn.

Nipari ọrọ rẹ, A l h a j i Adegbenro sọ pe, fun alafia ati irọrun Ipinlẹ Iwọ Orun on kesi Oloye Akintọla ati ẹgbẹ rẹ Dẹmọ pe ki wọn pe ipade igbimọ aṣofin ti Iwọ Orun were-were.

Alhaji D. S Adegbenro
Adele Olori Ẹgbẹ Afenifere

Alhaji Dauda Adegbenro ti iṣe adele babasale ẹgbẹ Afẹnifere ni o fi ọwọ si iwe na eyiti o ti sọ pe, ọdun ti alo lowo yi yio pari ni ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu yi, sibẹ koi ti si eto ni Ipinlẹ I w o Orun lati le pe ipade lati le jiroro lori inawo ọdun titun

Alhaji Adegbenro fi han pe, iyalenu nlala ni yio jẹ ti o ba jẹ wipe Ijọba Iwọ orun kọlati pe ipade Igbimọ Aṣofin yi, nigbati awọn Ijọba Ipinlẹ yoku nṣe tiwọn lọwọ o tun fi han pe ohun bubu ru ni yio jẹ bi awọn Ijọba Ipinle miran ba nṣe amojuto eto iṣe ile wọn ti o wa jẹ pe Ipinlẹ Iwọ Orun ni yio ṣe sekeseke nidi tirẹ

Alhaji Adegbenro wa fi han pe gbogbo awọn enia Ipinle Iwọ-Orun ni nwọn ti nke wipe, Ijọba ti ẹgbẹ Afẹnifere ni awọn nfẹ, nitoripe ẹgbẹ yi ni yio le ṣe amojuto gbogbo inira ti o ti wa fun wa lati ọjọ yi wa.

Nitori idi eyi, o sọ pe ki oloye Akintọla ati a w ọ n



Oloye S. L. Akintọla
Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria


## ATUN GBE DE !

Iwe Adura pataki fun Arisiki ati iṣẹgun lori ohun gbogbo lati ile Misirat, 2/6 Adura akanṣe ati apere ile aiye 2/- Ajọmọ-isin Ojiṣẹnla Mahammed 2/- Iwe Itumọ Ala ati Adura Ala ibanujẹ 4/6-

RANṢẸ TIRẸ SI:-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
Idumagbo Avenue Lagos Nigeria



## Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara!

Awọn Ẹgbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu ko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Ẹgbogi "Ikọ" ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibiti oti joko si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹn bere fun ẹgbogi wọnyi:

### "Thmo-Ephedrin" Tabi Ẹgbogi "Linituss"

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ agbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna-ọfun tabi pelu kelẹbẹ tabi ti o ma nje ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati loru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn ẹgbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara re iwọ yio si ri iyato gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti [illegible] nta kakiri

O daju nibe iwọ yio bere si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)



## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA, KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ un wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo gboẹda patapata" Amin.

"WAS SALAM"

AKIYESI Gbogbo Musulumi Ododo [illegible] oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA

Iye Owo 5/6, £3 fun dosini

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan



BI O BA NI

## Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi iṣẹ rẹ tabi oriṣiriṣi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**IWE Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NBGA

IROHIN KO TO AFOJUBA
Danwa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 563 TUESDAY MARCH 24, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni ongbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meji (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba


16, BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.


# ỌDỌMỌDE-'BINRIN KAN PỌKUNSO SINU IGBO

OWERRI:- Jinnijinni da bo awọn ara adugbo kan ti nwọn npe ni Amanachi nilu Owerri nigbati irohin kan nwọn pe ọmọge kan ti orukọ rẹ njẹ Agbone Chibokwu ti ojẹ ojulumọ larin ilu pokunso ninu igbo kan lẹba ilu ni ọjọ Ẹti ti iṣe ogunjọ oṣu yi.

Irohin awọn ọlọpa fi ye wa wipe ọmọge na jẹ ọmọ ọdun mọkanlelogun ati pe bi o ti gbajumọ to larin ilu oṣe ni awọn ọdọmọkunrin saba ma safun ti nwọn ko tilẹ le ba sọrọ fun ẹwa rẹ.

Onirohin wa fi ye wa pe lati igbati ọmọge na ti jade ni ile iwe nikan bi ọdun meji sẹhin ni o ti nwa iṣẹ ti koi ti ri iṣẹ kankan dimu awọn obi ọmọge yi waro pe gbogbo awọn ọrọ wọnyi ni oko idaamu ba ti ofi ro ara rẹ pin ti osi lọ pokunso.

Agbọ wipe awọn ọlọpa ti gbe oku ọmọge na lọ si ile iṣegun nibi ti nwọn yio ti ṣe ayẹwo diẹ lori rẹ ti nwọn yio si tun ma ṣe orisiriṣi iwadi lati le mọ ohun ti o faa ti ọmọbinrin na fi pokunso.

Bi nwọn ba ti wadi ọran na si ẹọ maa gbọ o.


AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid–Ul–Kabir Dance**

AT

**FORESTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn.

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rush'ng.

**Tickets: 4/– Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Offices, Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.


## Apapọ Ijọba Naijiria Fẹ Fi Owo Kun Owo Ọja


Lati Oju Ewe Kini


pe on ṣẹṣẹ ngbọ ọrọ na fun igba kini Ileyi ni.

O ni ẹnkẹni ko ba on sọ wipe awọn kan nranṣẹ fun awọn aloku taya mọto ni ilu Oyinbo. Oloye na ni on ko ri ọgbọn kan ninu ki enia ni ẹgbaa nile ki oluwarẹ o si tun maa wa ẹgbaa lọ si ode.

Oloye na ni o jẹ ohun iyanu lati ri wipe awọn kan nranṣẹ si ilu Oyinbo fun aloku taya mọto nigbati o jẹ wipe; taya mọto wa ni ilẹ yi.

Ni ipari ọrọ rẹ Oloye na ṣe ileri wipe on yio ri si ọrọ na Ijọba ko si ni gba ẹnikẹni laye lati maa ranṣẹ fun awọn taya mọto aloku ni Naijiria.

Lẹhin eyi ni awọn enia na tun wa kesi Oloye na wipe ki o ri si wipe owo awọn ọja ti nwọn nṣe ni Naijiria dinwo ku si ti awọn ọja ti nwọn nko wa lati ilu Oyinbo.

Bakanna ni awọn enia na tun ṣe alaye wipe o yẹ ki nwọn o maa ṣe awọn ọja ti wọn nṣe ni Naijiria dardara ju bi nwọn ti nṣe wọn bayi lọ.

Awọn enia tun ṣe alaye wipe iṣana ti nwọn nṣe ni Naijiria ko dara to eyiti nwọn nṣe ni ilu Oyinbo bẹni iye owo kanna ni nwọn nta awọn mejeeji.

Nwọn wa kesi Ijọba pe ki nwọn o ma ti mu aba lati fi owo kun owo ọja wa si Ile Igbimọ, ki nwọn o fi aba na sile di igbamiran, ṣugbọn Ijọba ti gba imọran na.

Oniwerohin wa kan fi ye wa wipe awọn ọlọja ti fi owo kun awọn ọja wọn lati bi ọjọ mẹta nigbati Ijọba ti fi owo kun owo Bode.

A lero pe gbogbo awọn ọja bi iṣana, ọṣẹ-Oyinbo, bisikiti, taya mọto ati bẹbẹ lọ ni yio tun le owo si lai peyi.

A gbọ wipe Ijọba ko le pa aṣẹ fun awọn onisowo pe iye kan ni ki nwọn o maa ta ọja wọn, ṣugbọn a gbọ wipe Ijọba yio moju to ti o fi jẹ wipe awọn onisowo ko ni fi owo kun iye ọja wọn ju iye-owo ti Ijọba fi kun owo ibode lọ.


**AKIYESI**

FUN IWADI, ITUMỌ ALA ATI IṢORO RẸ WA TABI KI O KỌWE SI: —WOLI ORIOLOWO AKINDELE ADEAGA COMPOUND ORILE—ILUGUN VIA—IBADAN



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495 Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) Bariga Yaba Lagos (24/3/64)